IRỌHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 776 FRIDAY AUGUST 21, 1964 (2D)

## Ẹni To Pe Abubakar Ni Ole Fi Poun Marun Jura

EBUTE — MẸTTA:— Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ile ẹjọ ni ki Ọkunrin kan ti o kegbe pe Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar ni Ole ni ile ẹjọ kekere ti Ebute Mẹtta lọ fi pọun marun tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu kan pẹlu iṣẹ alaṣekara.

Adajọ ile ẹjọ na tun sọ ninu idajọa rẹ pe ọkunrin na ko gbọdọ ba ẹnikankan fa rogbodiyan fun odindi osu mejila tabi pe ti o ba lu ofin na yio san ọgun pọnun lati fi tanra ki nwọn to jẹni iya sii.

Ọkunrin na ni Ọgbẹni Festus Araba eni ogun ọdun eyiti awọn ọlọpa fi ẹsun kan pe o lu ofin to le da rogbodiyan silẹ ni arin ilu Araba si gba pe on jọbi ẹsun na.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi nigbati Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar fẹ lọ ni Ikẹja lati lọ si Kaduna fun ipade kan ti awọn egbe olomi N P C ati ẹgba Dẹmọ N N D P fẹ lọ ṣe ni Ọkunrin na fa igbe ta ti o ni ole! ole!! ole!!! eyiti awọn ọlọpa yara tete mu ọdaran na ni adugbo Denton Street, Ebute Mẹtta.

# IDIBO APAPỌ YIO WAIYE L'OṢU KỌKANLA ỌDUN YI



Alhaji AHAMDU BELLO

KADUNA:- Ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi N P C ati awọn alabaṣepọ wọn ẹgbẹ Dẹmọ N N D P ẹgbẹ M D F ati awọn iyoku wọn ni irohin ti de ọwọ wa labẹlẹ nibi ipade na ni a ti gbọ pe eto idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba Naijiria yio waiye ninu oṣu kọkanla ọdun yi ati pe awọn ẹgbẹ Olomi N P C ati awọn alabaṣepọ wọn ti jinroro lori eto idibo na nibi ipade ti awọn Olori ẹgbẹ na nṣe lọwọ.

Irohin na tun fi ye wa siwaju si pe awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi N P C ati awọn alabasowọpọ wọn ti bẹrẹ ipade na ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ na si nba eto ọrọ wọn lọ lori imura silẹ ati adehun ti awọn ẹgbẹ na yio si jijọ fi ọwọ si lati mọ ero ajumọṣepọ wọn lasiko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria na eyiti yio waiye ninu oṣu kọkanla ọdun yi gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ labẹlẹ na.



OLOYE AWOLỌWỌ



Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa
Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria

Ninu awọn adehun ti awọn Olori ẹgbẹ Olomi N P C ba awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ N N D P, M. D. F. N D C (Niger Delta Congress) ṣe lori eto adehun na nibi ipade wọn na ni Kaduna eyiti awọn Olori awọn ẹgbẹ na jijọ lero pe nwọn ṣe ni;

Ninu awọn ọrọ awọn ọmọ ọgbẹ jinroro lori le ni pe to ba di asiko ti ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba yio ṣe ipade eyi to nbọ yi pe awọn ọmọ ẹgbẹ na yio sọrọ lori idasilẹ ipinlẹ kan ti anwọn yio ma pe ni "Calabar State" ati River State" eyiti yio jẹ pe nwọn yio ya kuro lara ipinlẹ Ila Orun Naijiria, Iwọ Orun Naijiria ati Agbedemeji piinlẹ Iwọ-Orun Naijiria.

Awọn ẹgbẹ na tun sọ ninu ipade wọn na pe awọn ọmọ ẹgbẹ yio pari ija kan to wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ M. D. F. larin Ọgbẹni John Edokpolor ati Ọgbẹni James Otobo Irohin na, fi ye wa labẹlẹ pe awọn ẹgbẹ na yio fun Ọgbẹni John Edokpolor ni ipo Oludasilẹ ẹgbẹ M. D. F. ati Ọgbẹni James



## Iforukọ Silẹ Awọn Ọmọde Yio Bẹrẹ L'ọsẹ Ti Mbọ

EKO:- Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni irohin de ọwọ wa lati ile iṣẹ Ala oso to ẹkọ fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria pe eto fifi orukọ awọn ọmọde ti yio bẹrẹ ile ẹkọ ninu ọdun to nbọ yio bẹrẹ ni ọjọ kẹrindinlelogun, si ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi lati agogo mẹjọ owurọ si agogo mẹwa ati lati agogo mẹrin irọlẹ si agogo mẹfa irọlẹ fun odindi ọjọ mẹta, Irohin na tun fi ye ni pe obi ti o ba kuna lati fi orukọ ọmọ silẹ fun ọjọ mẹta nwọnyi ko le ni anfani ẹkọ ni ilu Eko ati agbegbe rẹ l'ọdun ti nbọ.

Irohin na tun fi ye ni pe ọmọ ti nwọn ni lati fi orukọ silẹ fun ile ẹkọ lọdun ti nbọ ni lati mu awọn ọmọ na lọwọ ati pe ki iṣ pe fun obi ti yio sọ pe on ti ngbe ni ilu Eko ni kan ṣugbọn awọn obi ọmọ ni lati ri i pe ọmọ ti yio bẹrẹ ile ẹkọ lọdun ti nbọ na ni lati kọ nọmba nitori arun ajakalẹ.

Awọn Obi awọn ọmọ tabi Alagbatọ ni lati ri i pe awọn ọmọ ti nwọn fẹ fi orukọ rẹ silẹ na ti mu iwe ẹri ọjọ ibi rẹ lọwọ lọ si awọn ile ẹkọ ti nwọn yio ti fi orukọ awọn ọmọ silẹ fun ile ẹkọ ni ọdu ti nbọ.

Irohin na tun fi ye ni pe awọn Obi tabi Alagbatọ ti ngbe agbegbe rẹ ko lẹtọ lati fi orukọ ọmọ rẹ silẹ.

Irohin na tun fi ye ni pe lai je pẹ o han gedegbe pe awọn Obi tabi Alagbato si wa ngbe ni Eko laseko ti ifi orukọ awọn ọmọ sile bọrẹ ati pe lai jẹ pe awọn obi ọmọ na ti ngbe ni Eko lati ibẹrẹ ọdun 1964.

Awọn ọmọ ile ẹkọ to ti wa ni ile ekọ tẹle ko ni anfani lati tun lọ orukọ silẹ gẹgẹbi ẹni pe o ṣẹṣẹ fẹ bẹrẹ ile ẹkọ Irohin lati ile Alakoso eto ẹkọ ti apapọ Ijọba ile Naijiria na tun se ikilọ pe eniti ba gba ọna eto fi orukô ọmọ silẹ fun ile ẹkọ lodun ti nbọ na ni lati jiya lori eto to ba ofin

# ỌTẸLẸMUYẸ EKO

## Egbẹ Oṣewe Yoruba Nkọ ?

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu kejọ ọdun yi ni Ọtẹlẹmuyẹ Eko wọle to gbẹrẹ bi ẹniti ẹgbẹ ndun. Mo ki i, o si ki emi na, Mo wa bere lọwọ rẹ pe a ma ri yin loni "Muyẹ Ọkunrin" osi dami lohun pe bẹẹni ọrọ kan ni on wa bere lọwọ mi. Ni mo ba sọ fun pe ki o niṣo nile. Nwọn yi ni awọn ibere rẹ ati esi ti mo fun.

### Awọn Ibere Ọtẹlẹmuyẹ Eko

Ọtẹlẹmuyẹ :- Ẹku deede iwonyi o Olotu, ṣe ara le dada ?

Olotu :- Iyawo ni o le sọ bi ara mi ti le to, ko si nkankan lara mi o.

Ọtẹlẹmuyẹ :- Lori ọrọ nipa dida ẹgbẹ oṣewe Yoruba silẹ ti Ọgbẹni J. O. Shoyinka nkede rẹ lojojumọ ninu iwe irohin Yoruba ati Imọlẹ ni mo ṣe wa ba nyin

Olotu :- Inu mi dun lati gbọ bẹ ẹ nitoripe ẹni mi ni Ọgbẹni ti o daruko yẹn.

Ọtẹlẹmuyẹ :- Ọrẹ mi gidi ni Ọgbẹni Shoyinka na ise, biko ba ri mi ni iṣẹju kan yio kan mi lara bi ọgan. Bi o ti kalariri mi to, bi o tilẹ wa lẹgbẹ iyawo lọganjọ oru bi mo ba kan ilẹkun kokooko, piri ni yio si fun mi tabi kilo tun ku ?

Olotu :- Inu mi dun lati gbọ bẹ ẹ ki i wọn lọdọ emi na. Kini o fẹ sọ si ọrọ dida ẹgbẹ Osewe Yoruba na silẹ ?

Ọtẹlẹmuye :- Ohun ti mo fẹ sọ si ni pe lati igbati Ọgbẹni Shoyinka ti nṣenumọ idasilẹ ẹgbẹ awọn oṣewe Yoruba ko kọ ibi ara si to

Olotu:- Bawo ni o ṣe mọ pe wọn ko kọ ibi ara si ?

Ọtẹlẹmuyẹ: Ohun ti mo fi mọ pe nwọn ko kọ ibi ara si to ni pe, a ko gbọ pe nwọn ti da ẹgbẹ na silẹ bi ọgbẹni Shoyinka ti nṣenu mọ to.

Olotu:-Ododo ọrọ ni o sọ Ọtẹlẹmuyẹ ye. Emi papa ti kin ọrọ Shoyinka lẹhin titi ṣugbọn a ko ri ki awọn osewe wa lede Yoruba ji giri.

Ọtẹlẹmuy :- Aseko ti emi yio tẹsẹ bọ ọrọ yi ni nwọn yio to ji giri

Olotu- Ngo wipe o wi bẹẹ Odumare ko fuu ọ ṣe

Ọtẹlẹmuyẹ:-Amin ati amin

Olotu:-Nigbawo ni o ti ri Ọgbẹni Shoyinka nı gbẹhin?

Ọtẹlẹmuyẹ-:Mo ri ni ana a si jijọ fi ọrọ jọmitoro ọrọ lori idasilẹ ẹgbẹ oselu na

Olotu:- Kini o tun wi

Ọtẹlẹmuyẹ:- Ọrọ pọ ninu iwe kọbọ, ohun ti owọ ati eyiti mo bere lọwọ rẹ ni yi o Olotu

### ỌTẸLẸMUYẸ PADE SHOYINKA

Ọtẹlẹmuyẹ: Ẹku ọginnitin yi o Shoyinka, ṣe ko de ọdọ nyin o?

Shoyinka:-Nko tilẹ mọ chu ti o njẹ ọginnitin nitoripe mo ti fi ẹkọ irọmi gbe ọbẹ ti oyinbo



ỌGBẸNI ẸRUKOBODO
Osewe Yoruba

pe ni 'Pepper Soup" dasi ki nto bẹ sita. ni onuro yi iwọ ni mo le bere lọwọ re pe ṣe o ko ri ututu yi.

Ọtẹlẹmuyẹ- oginnitin kẹ, nigbati o jẹ wipe ẹgbẹ pasero mi ni mo ti dide lowuro yi, nko tilẹ mọ ohun ti o njẹ oginnitin mo fẹ yara de ibikan pa a ṣu gbọn kini ẹ ti gbọ nipa ọrọ ida silẹ ẹgbẹ oṣewe Yoruba si ?

Shoyinka -Emi ati ẹlẹgbẹ mi oṣewe Yoruba kan ti falọwọ a o si ri pe a da ẹgbẹ na silẹ ninu oṣu yi lagbara oluwa

Ọtẹlẹmuyẹ -Ti ẹ ba tele da ẹgbẹ na sile anfani nlanla ni yio je fun ọmọ Yoruba.

Shoyinka -Bẹẹni ọpọlọpọ anfani ni o wa nibe Ekini Awọn ọmọ yoruba yio ni anfani ati ma a kọ ede ijinle yoruba.

Ọtẹlẹmuye -Mo kin ọrọ ti o wi yi lehin ṣe bi awọn Ghana ati India ti lesa mo ede wọn kikọ ni yẹn ju ede elede lọ.

Shoyinka -Woyika lode on ọpọlọpọ ọmọ Yoruba gidi haun ni o mọ ede Yoruba ka ti a ti kọ si di iṣe pelu.

Ọtẹlẹmuyẹ- O ko purọ Shoyinka Yoruba kan ẹẹsi kan ni nwọn fi nbọ ara wọn larin sọrọ :

Shoyinka -Eyi ni Yoruba npe ni a m u l u m a la Yoruba tabi adamọdi Yoruba.

Ọtẹlẹmuyẹ Eyi ko ṣe gbọ lati ri pe ọmọ Yoruba ko mọ ọ sọ tabi pe ko mọ ka Shoyinka

Shoyinka- Kini anfani ọmọ yoruba ti ko mọ ede baba rẹ fọ!

Ọtẹlẹmuyẹ:- A ni ọpọlọpọ ntiju lati maa sọ Yoruba ede abunibi wọn

Shoyinka Ẹ ko purọ ọtẹlẹmuyẹ' ọpọ sọ Ovinbo jọ "Ọpẹrẹ" lu si ọfisi kakiri, iwọ yio ba wọn nibe repete.

Anfani keji ti o tun wa ninu idasilẹ ẹgbẹ yi ni pe, Ọpọlọpọ awọn ọmọ yoruba ni nwọn ni ọpọlọ lati ṣe orisirisi iwe, ṣugbọn ti nwọn ko ni owo lọwọ lati fi tẹ jade fun ida ẹgbẹ bayi sile nwọn yio le maa se iranlọwọ lati ba iru enia bẹẹ tẹ jade fun tita

Ọtẹlẹmuyẹ; A ni ọpọlọ to pe ju ti Alajọ Somolu lọ koko ọrọ gan ni o sọ.

Shoyinka : Nipa isẹ bayi awọn oṣere wa bi ọgbẹ ni Ogunde, yio maa ni ọpọlọpọ awọn iwe ti awọn oniwe wa ba nṣe lo un re rẹ.

Ọtẹlẹmuyẹ;-Bẹni, ọrọ rẹ ko se, nigbati o ba ya ti awa na nṣere sinu Sinima. Ti a ba si bẹrẹsi lo iwe ti awọn aṣewe wa ṣe. ko ni lẹgbẹ ni gbogbo agbaiye

Shoyinka:- Wo iru iwe bi Ogboju odẹ ninu Igbo Irunmale,

Njẹ ki nwon fi iru yẹn sere ninu Sinima" bawo ni o rope yio ti dun to?

Ọtẹlẹmuyẹ.- Ere oloyinmọmọ ni yio jẹ. Olotu ajumọsọpọ emi ati Shoyinka niyẹn, a o ma reti idasilẹ ẹgbẹ na.

Olotu:- Gbọ bi Ọgbẹni Shoyinka ti wi yẹn, toripe aleẹi leṣe ni. Ka fi rere pade o. ... n o w ...


## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti nyọ e lẹnuto kan bi ọdun kan tabi ju ẹ lo awọn egbogi iro i ni ese iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, lu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun In otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iil , Ikọ ti o mu mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pelu.

Bi o ba an lgo kan PORAL yi wa lọwọ na yio ri a i tọ ninu ara rẹ ui kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patipata iwọ yio ma jeundara dara iwọ yio si un fonfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Lab gi Ikọ miran ni ọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji) .. ..

Adedun Chemist

# Aya Di Ọlọpa nu Ile

Lati Ọwọ HADJI Y, A. DISU

Asifẹ pupọ ni fun obinrin rere lati lọ fẹ ọkunrin jandukụ, ọkọ opurọ ati ọkọonisọndisọndi. Ori buburu si ni o jẹ fun obinrin na. Bi ọkunrin ire ba si lọ fẹ obinrin buburu, asifẹ ni o jẹ fun ọkunrin na.

Bakana ni, ori buburu si ni o nje f u n u n. Oluwa rere, a fi ọla Rẹ bẹ ẹ, a fi Akẹhinde Anab Muhammed, ki ikẹ ati ọla ma ba a titi lailai, bẹ Ẹ, maṣe jẹki a si ọkọ ni, ma si ṣe jẹki a si aya ni o. Amin.

Ọkọ buburu a ma ṣi aya ire lọna. Aya buburu a si ma a ṣi ọkọ ire lọna, fun apẹrẹ, baba dudu omiran kan mbẹ lasiko kan. Onisọndisọndi enia ni, onijibiti ni, opurọ pupọ ni. Ẹniti o ba si purọ mọ, Ọlọrun ni Ọba alaabo ti o le koo yọ Afinju atọrọjẹ si ni. Baba "rigimọ si ni o jẹ. Baba na si fẹ aya doogo adelebọ kan ti o ṣe enia ti o si fẹran lati maa sọ otitọ, o si fẹran lati maa h u iwa ire pẹlu.

Nwọn bi aya rẹ ni idi baba ati i y a dada. Iran Ọba ati ojoye kan ni awọn obi rẹ na. Ṣugbọn oni idi igi kan ti o nda ileru n i ọkọ na. Okuroro si ni o jẹ

A m a buramuramu b i kinihun lori irọ. Bi o ba si pe iyawo rẹ lati jẹri eke, bi iyẹn ko ba si ṣe bẹẹ, yio bẹrẹsi kanra, mọ. Nigbati obinrin na ko si fẹ ki maa ko akoka, os i bẹrẹsi jẹri eke lati le tẹ ẹ lọrun. Kariikafọ, obinrin na si di opurọ ati eke. O si di ọlọpanu ile, lati l e tẹ ọ k ọ rẹ lọrun.

O tọ ki ọkunrin rere fẹ obinrin ire, ki obinrin ire si fẹ ọkunrin ire Ki ọmọ obinrin ti obi rẹ jẹ oni mimọ fẹ ọmọ ọkunrin ti o bi rẹ jẹ onimimọ K i ọmọ ọkunrin Dokita Elaias fẹ ọmọ obin in Dokita Coker Apẹrẹ ni eleyi o Ika ti o ba wọ imu ni a gbọdọ kiwọ iho imu



Aihaji Y, A. Disu

Ọkọ ire ati aya ire yio so eso ire Ọkọ buburu ati aya buburu yio so eso buburu bakanna.

---


# Akiyesi

Si Gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ni Abẹokuta eti agbegbe rẹ Ti o ba fẹ ra Irohin Imọlẹ ti o nj de ni Ojojumọ lọ ra lọwọ Aṣoju wa Omidan Owokoya.

Owo Bookshop
Shapon Ago - Oko Road
ABEOKUTA

Ti Enikeni ni Irohin Imọlẹ kọbọ meji pere.



BERE EGBOGI

## "VERMIZYN"

Ojulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARON latanlatan tabi arọn kinisa tioma mu idiwọ wa fun ẹgbagbeje obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.

Bẹsi ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu Igba-aya, ọua ọfun, sisọ lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji irufẹ egbogi arọn yi kosi ni gbogbo ilẹ Naigeria jakejo iṣẹ rẹ si daju

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe oti re eekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi aaan yi gẹgẹbi awọn Jaman iti oṣe ti juwe lilo rẹo Fun agbalagba nikan ni owa fun. Bere orişirişi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Store;
8, Palmchurch Stree Lagos P O Box 333
Phone: 22878 Najeria (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMISTS.
4, Workeman Street Yaba, Phone 44166

Iṣẹ Olodumare Dispensary Okebọla Ibadan.


---


## OLUSHI SOCIALISTS

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

**at Foresters Centenary Hall**
22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p, m. till dawn

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises**
**Bashy & His Young Stars Orchestra**

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana. Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**
**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lagos Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 776. FRIDAY, AUGUST 21 1964 (2D)


## Oloye Benson kilọ Fun Awọn Olotu Iwe Irohin

EKO ;- Alakoso eto Irohin fuu apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati igba kẹta Olori ẹgbẹ AlaKukọ Oloye T. O. S' Benson kilọ fun awọn Olotu Iwe Irohin lori Ọrọ Olotu'' ti awọn fi ma a nkọlu awọn enia.

Oloye Benson sọrọ le ọrọ Olotu ti iwe Irohin kan ti a npe ni Daily Telegraph'' eyiti Oloye Benson sọ pe nwọn sọ ninu ẹrọ asọrọmagbesi eyiti o sọ pe i ko jẹ ohun to tọna lati ma kọlu enia lori ọrọ inu ẹrọ na.

Oloye Benson sọ pe ti jẹ pe awọn Olotu iwe Irohin tete dopin ọrọ Olotu wọn eyiti nwọn fi nkọlu enia pe ẹrọ Asọrọmagbesi ki yio da a duro lati ma sọ ọrọ Olotu ninu ẹrọ Asọrọmagbesi

Oloye Benson sọ pe ọrọ olotu ko mu ki awọn olotu iwe irohin fi ma kọlu awọn enia bi ko sẹ pe ki nwọn fi ma tọ awọn enia soju ọna to tọ ati eyi to ye ati pe ti nwọn ba ri nkan ti ko tọna lati fiye agbaiyẹ

Ni ikehin ọrọ rẹ Oloye Benson kesi igbimọ awọn ẹgbẹ onirohin lati ri pe nwọn lo ipo wọn rere lati ri pe nwọn ko fi ọrọ olotu ninu awọn iwe irohin ma ọlu enia ati pe ki awọn ẹgbẹ onirohin wa tete ri si iwa awọn olotu iwe irohin lati tete le, dẹkun iwa na.

### Iyaafin Awolọwọ Sọ Pe

# Akintọla Lo Ba Iṣẹ Ilọsiwaju Awolọwọ Jẹ Ni Iwọ Orun

IJERO-EKITI:- Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Oloye iyaafin H. I. D. Awolọwọ sọ nibi ipade kan ti o ba awọn enia ilu Ijero Ekiti larin eto irin ajo rẹ si ẹkun Ekiti pe awọn iṣẹ ti o le mu ilọsiwaju ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria laseko ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ wa gẹgẹbi Alakoso Ijọba ipinlẹ na pe lẹhin ti Oloye Awolọwọ fi aye na silẹ fun Oloye S. L. Akintọla gẹgẹbi Alakoso ipinlẹ na lo ba ipinlẹ na jẹ.

Nigbati Iyaafin Awolọwọ sọ eyi fun awọn enia ilu Ijero Ekiti ni nwọn ba fa igbe ta pe, Awo! Awo!! Awo!!! Iyaafin Oloye Awolọwọ si tun fi ye awọn enia na pe nigbati Oloye S. L. Akintọla gba ipo gẹgẹbi Alakoso ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni eto aje, alafia ilọsiwaju ati ilera ipinlẹ na parun patapata lati ọdun 1960

Oloye iya afin Awolọwọ fi ye awọn enia na pe ohun to le mu ki Ijọba rere wọ ipinlẹ na ni pe ki awọn enia ipinlẹ na jẹ ki oloye Akintọla ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ kuna laseko idibo to nbọ yi ati pe nkan to le gba ipinlẹ Iwọ Orun silẹ lọwọ airi jẹ ati airi mu niyẹn.

Lẹhin ti Oloye iyaafin Awolọwọ ka awọn iṣẹ rere ti Oloye Awolọwọ ṣe si ipinlẹ na laseko tirẹ, Iya afin Awolọ ṣe si ipinlẹ na lasiko tirẹ, iya afin Awo ọwọ sọ pe ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan lo le gbe ogo ipinlẹ na yọ

Nigbati iyaafih Oloye Awolọwọ tun nṣ ye awọn enia Ijero Ekiti lori gẹgebi nwọn sẹ da ẹgbẹ Dẹmo N. N. D P. silẹ iyaafin Oloye H. I. D. Awolọwọ sọ pe ẹgbẹ ti nwọn fi iwa ọdalẹ da silẹ lati le ti ba emi isọkan ati ilọsiwaju awọn ọmọ ilẹ Yoruba jẹ ni.

Oloye iyaafin Awolọwọ un ṅ ye awọn enia ilu na pe ki nwọn fi tokantokan fara ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre le gba gbogbo awọn nkan tọ ti ṣ,ẹgbẹ paSa.

Gloye iyaafin Awolọwọ tun se apejiwe ọrọ ti iyaafin Faderera Akintọla sọ lori owo ti o sọ pe awọn ẹgbẹ Afenifẹre ṅ pamọ si ile ifoopamọ kan ni ile Geesi iya afin Awolọwọ sọ pe iro patapata ni ọrọ ti iyaa in Akintọla sọ ati pe ọrọ ikomo ni ọrọ rẹ patapata ati lati ṅ ba ẹgbẹ Afẹnifẹre jẹ.

Nigbati Oloye iya afin Awolọwọ de Ikoro Ekiti ni nwọn ṅ oye da a lọla gẹgẹbi ,,Eye Abiye'' ti ilu Ikoro Eketi. Ẹniti o fi iya afin Awolọwọ joye na ni Iya afin Tinuade Aina ọ'an ninu awọn Oloye Obinrin ni ilu na nwọn si ti fun iya afin Awọlọwọ ni ilẹkẹ Iyun fin ti amin oye ti o jẹ na.

Ni Ado - Ekiti ni irohin ti de ọwọ wa pe iya afin Oloye Faderera Akintọla ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ pe awọn Obinrin ọlọja si bẹrẹ si sọ okuta lu wọn nigbati nwọn de ilu Ado-Ekiti. Awọn Obinrin na ti mura pẹlu okuta ati ada lati gbogun ti iya afin Akintọla ati awọn enia rẹ.

## Dokita Obi Lọ Ba Egbẹ N· P. C. Ṣe Ipade

Olori ẹgbẹ Dynamic Party ati Olukọ ni ile ẹkọ gigati Univfasiti Ibadan tẹlẹ Dokita Chike Obi n irohin tun fi ye wa pe o lọ si Kaduna ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria lati lọ ba wọn ẹgbẹ Olomi N. P. C. ati awọn alabaṣepọ wọn ṣe ipade nibi ti awọn Olori ẹgbẹ na ti nṣe ipade lati ọjọ Aku ti iṣe ọjọkẹjidinlogun oṣu yi ni il Olori ẹgbẹ Olomi Alhaji Ahmadu Bello Sardauna ilu Sokoto.

Irohin fi ye wa pe Dokita Obi si nlọ lati lọ ṣe eto gẹgẹbi ẹgbe rẹ yio ṣe papọ mọ ẹgb; Olomi laseko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria. Irohin na tun fi ye wa pe nwon ti nreti Dokita Obi ni Kaduna nigbati ipade na ti bẹrẹ.

Ni ọjọ kokandinlogbọ oṣu tolọ ni Dokita Obi sọ ninu ọrọ rẹ ni Eko pe ajumọṣepọ ẹgbẹ on ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ba jẹ lori pe awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe adehun lati papọ mọ ẹgbe Alakukọ.

Dokita Chike Obi tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ lasiko na pe on to mu on sọ pe ẹgbẹ on ko ni ba egbe Ọlọpẹ ṣe pọ ni pe awọn Afenifẹre kuna lati sọ fun ẹgbe on ki nwọn to dapọ mọ ẹgbẹ Alakukọ (N C N C).

Ninu ipade ti Dokita Obi yio ṣe ni awọn eto lori ajumọṣepọ ẹgbẹ rẹ pẹlu N P C si je ohun to wa ni aṣiri ati pe awọn ẹgbẹ na ko ti sọ nkankan si ode lori ipade na.

Gegebi irohin to de ọwọ wa pe awọn ẹgbẹ na pin ara wọn si ọna mẹrin lati lọ jinroro lori ajumọṣepọ ẹgbẹ wọn ati pe awọn ẹgbẹ na to pin ara wọn si ọna mẹrin yio jijọ papọ lati le jinroro lori eto adehun ti nwọn sẹ ninu awọn ipade ti nwọn pin ara wọn si.

## LATI OJU EWE KINI

Otobo yio wa gẹgẹbi olori ẹgbẹ M. D. F (Mid West Front).

Irohin na tun fi ye wa labẹlẹ pe ẹgbẹ Olomi N. P. C. lodi si eto Ijọba apapọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu Take jado ilẹ Naijiria lai ko si alatako kankan ninu Ijọba ilẹ Naijiria ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ N. P. C. sọ pe pe yio jẹ ohun yio mu ẹgbẹ wọn kuna ori eto wọn ti nwọn tẹ ṣe silẹ. Awọn ọmọ ẹgba N. D C. sọ ninu ipade ni pe nwọn ni lati ma asan owo ọọya fun ilu to jẹ pe awọn ti nri epo mọto wa jade gẹgebi nkan to jẹpe o ba eto lọ.

Irohin fi ye wa lati ọwọ Oniwe Irohin ni Kaduna pe ko ti si Ironin kan to je pe awọn ẹgbẹ na si ti gbee jade lori eto adehun ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe nibi ipad wn na o to nlọ


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 21/8/64